# IṢẸ IYANU KIN-IN-NI TI JESU ṢE ATI WÍWẸ TẸMPILI MỌ́

**Johannu 2:1-25**

**ẸKỌ 28 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "O si nkọ́ni, o nwi fun wọn pe, A ko ti kọwe rẹ̀ pe, Ile adura fun gbogbo orilẹ-ède li a o ma pè ile mi?" (Marku 11:17).**

**I Igbeyawo Ni Kana Ti Galili**

1 Iyá ati awọn ará Jesu wà nibi igbeyawo naa, Johannu 2:1, 12

2 A pe Jesu ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ sibi igbeyawo naa, Johannu 2:2

3 Ẹ̀bẹ̀ Maria ati ibawi pẹlẹ ti Jesu ba a wi, Johannu 2:3, 4

4 "Ohunkohun ti o ba wi fun nyin, ẹ ṣe e," Johannu 2:5; Matteu 7:24-27

**II Iṣẹ Iyanu Ti Jesu Ṣe ni ibi Igbeyawo**

1 Jesu paṣẹ fun awọn iranṣẹ lati pọn omi kún awọn ikoko, Johannu 2:6, 7

2 A sọ omi naa di waini a si bu u lọ fun olori àsè, Johannu 2:8

3 Didara rẹ̀ tayọ waini ti akọkọ, Johannu 2:9, 10

4 Ogo Rẹ̀ fi ara hàn fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ nipa iṣẹ iyanu naa, Johannu 2:11

**III Wíwẹ Tẹmpili Mọ́**

1 Jesu rin lọ si Jerusalẹmu fun Ajọ Irekọja, Johannu 2:12, 13

2 O ri maluu, agutan, ẹyẹle ati awọn onipaṣipaarọ owo ni Tẹmpili, Johannu 2:14

3 A lé awọn arufin naa jade a si yí tabili awọn onipaṣipaarọ owo naa dànu, Johannu 2:15, 16

4 "Ẹ máṣe sọ ile Baba mi di ile ọjà tità" Johannu 2:16, 17; Matteu 21:13

**IV Awọn Ju Beere Àmi Àṣẹ**

1 "Àmi wo ni iwọ fi hàn wa?" Johannu 2:18; Matteu 12:38-42

2 "Ẹ wó tẹmpili yi palẹ̀ … Emi o si gbé e ró" Johannu 2:19

3 "Ṣugbọn on nsọ ti tẹmpili ara rẹ̀" Johannu 2:20-22

4 Ọpọlọpọ jẹwọ pe wọn gbagbọ́, ṣugbọn Jesu mọ ọkàn wọn, Johannu 2:23-25

## ALAYE

Ninu akọsilẹ iṣẹ iyanu kin-in-ni ti Jesu ṣe, a ri ibalò Rẹ̀ pẹlu awọn eniyan. Jesu kò gbé igbesi-ayé ifara-pamọ. O dara pọ̀ pẹlu gbogbo eniyan. Nigba miiran o bá awọn agbowode ati ẹlẹṣẹ jẹun. Awọn ẹlomiran ni igba aye Rẹ̀ rò pe o yẹ ki O yẹra fun wọn, wọn si pe E ni "ọjẹun ati ọmuti, ọré awọn agbowode ati awọn ẹlẹṣẹ" (Luku 7:34). O gbé laaarin awọn eniyan gẹgẹ bi ọ̀kan ninu wọn. Nitori ifaramọ timọtimọ ti o wà laaarin Jesu ati awọn eniyan, Paulu le wi nipa Rẹ̀ pe: "Nitori a kò ni olori alufa ti kò le ṣai ba ni kẹdun ninu ailera wa, ẹniti a ti danwo li ọna gbogbo gẹgẹ bi awa, ṣugbọn lailẹ̀ṣẹ" (Heberu 4:15). "Nitorina o yẹ pe ninu ohun gbogbo ki o dabi awọn ará rẹ̀, ki o le jẹ alãnu ati olõtọ Olori Alufa" (Heberu 2:17, 18).

Iṣẹ iyanu ti Jesu ṣe ni Kana fi hàn pe O fi ọwọ́ si igbekalẹ ti Ọlọrun dá silẹ, ti ki si i ṣe eniyan (Gẹnẹsisi 2:24). A tun fi ogo Rẹ̀ hàn fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ninu iṣẹ iyanu yii (ẹsẹ 11). Kana ti Galili to mile mẹrin si Nasarẹti nibi ti a gbé tọ́ Jesu dagba. Bi o ti lẹ jẹ pe Jesu ko i ti ṣe iṣẹ iyanu kan titi di akoko yii, iyá Rẹ̀ tọ Ọ lọ ni akoko aini yii o si wi pe, "Nwọn kò ni waini." O gbagbọ́ pe O le ṣe nnkan kan nipa rẹ̀. Maria mọ̀ pe Kristi ju eniyan lasan kan lọ. O ti ro ohun pupọ lọkan nipa Rẹ̀ (Luku 2:19, 51).

Jesu, gẹgẹ bi ọmọ eniyan, jẹ ọmọ Dafidi ati ọmọ Maria; ṣugbọn nitori O jẹ Ọmọ Ọlọrun, Oluwa Dafidi ni i ṣe, eyi ti Dafidi tikara rẹ̀ jẹwọ (Marku 12:35-37; Ifihan 22:16), O si tun jẹ Oluwa iya Rẹ̀ pẹlu. Nigba ti o ba kan ohun ti o jẹ mọ́ ohun ti Ọlọrun, kò jafara lati gbà ipò ti o tọ́ si I. Nigba ti o di ọ̀ran iṣẹ iyanu, ti o jẹ mọ ipò Rẹ̀, gẹgẹ bi Ọmọ Ọlọrun, idahun Rẹ̀ pe -- "Kini ṣe temi tirẹ, obirin yi?" – dabi eyi ti o fi hàn pe ni rireti iṣẹ iyanu, Maria fẹ ṣe rekọja sinu agbara atọrun-wá Jesu nipa eyi ti Oun kò si labẹ aṣẹ iya Rẹ̀.

Maria kò sọ̀rọ mọ́ si Jesu, ṣugbọn igbagbọ́ rẹ̀ mu ki o wi fun awọn iranṣẹ naa pe, "Ohunkohun ti o ba wi fun nyin, ẹ ṣe e."

Iṣẹ iyanu yii ṣe lai si aṣehan kan. Awọn ikòkò mẹfa wà nitosi, ọkọọkan si gbà to garawa mẹfa tabi ju bẹẹ lọ. Jesu sọ fun awọn iranṣẹ naa lati pọn omi kún wọn, lẹyin naa ki wọn bu u, ki wọn si gbe e tọ olori àse lọ. Olori

àse pe e ni waini rere.  Ni gbogbo akoko iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀, Kristi kò ṣiṣẹ iyanu kan ki awọn eniyan ba le ri I, ṣugbọn kò kuna nigba kan lati tẹ́ olukuluku lọrun ninu aini wọn.

Nitori Jesu sọ omi di ọti waini, awọn ẹlomiran fẹ́ maa titori bẹẹ mu ọti ninu awujọ ati lati maa mu ọti amupara. O lodi si ẹ̀dá Kristi ati si gbogbo iṣẹ Rẹ̀ ni aye lati ṣe ọti ti o le pa ni lara, tabi ti o le mu ọti pa ni.  Gbogbo iṣẹ iyanu Rẹ̀ jẹ iṣẹ aanu.  Bibeli bá mimu ọti amupara wi.  "Ẹlẹya li ọti-waini, alariwo li ọti lile, ẹnikẹni ti a ba fi tanjẹ kò gbọ́n" (Owe 20:1).  "Máṣe wà ninu awọn ọmuti; ninu awọn ti mba ẹran-ara awọn tikarawọn jẹ" (Owe 23:20). "Tali o ni òṣì? tali o ni ibinujẹ? Tali o ni ijà? Tali o ni asọ̀? Tali o ni ọgbẹ lainidi, tali o ni oju pipọn.  Awọn ti o duro pẹ nibi ọti waini, awọn ti nlọ idan ọti waini àdalu wò.  Iwọ máṣe wò ọti-waini pe o pọn, nigbati o ba fi àwọ rẹ̀ han ninu ago, ti a ngbe e mì, ti o ndùn" (Owe 23:29-31).  Tun wo Isaiah 5:11;  Romu 13:13;  1 Kọrinti 6:10; ati Efesu 5:18.

Ninu iwe atumọ ède, a kà pe oje esokeso tabi igi eyikeyi ti a fún fun mimu ti kò bà ni a le pe ni waini.  Omi ti Jesu sọ di waini yii ni a fi fun awọn eniyan lẹsẹkan naa, lai si aniani o wà ni titun, kò si ti i bà.

Lẹyin igbeyawo, Jesu sọkalẹ lọ si Kapernaumu leti bèbè odo Galili pẹlu iya rẹ̀ ati awọn arakunrin ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀.  Nihin ni ile Peteru ati Anderu, bẹẹ naa ni Kapernaumu jẹ ibi ti Kristi ti ṣe ọpọlọpọ iṣẹ iyanu nigba pupọ leralera.  Ṣugbọn ọjọ naa de nigba ti Jesu dá awọn ara ilu yii lẹbi nitori wọn ko ronupiwada.  "Ati iwọ, Kapernaumu, a o ha gbé ọ ga soke ọrun? a o rẹ̀ ọ silẹ si Ipo-oku: nitori ibaṣepe a ti ṣe iṣẹ agbara ti a ṣe ninu rẹ ninu Sodomu, on iba wà titi di oni" (Matteu 11:23).

Lati Kapernaumu, Jesu lọ si Jerusalẹmu si Ajọ Irekọja kin-in-ni ti o kọ́ ṣe nigba ti O bẹrẹ iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀ ni gbangba.  Nigba ti O de Tẹmpili, O ri i pe awọn onipaṣipaarọ owó ti sọ ọ di aimọ́.  Nitori a n fi ẹran rubọ ni Tẹmpili ni awọn oniṣowo ṣe mu anfaani yii lò lati maa ta ẹran ninu Tẹmpili.  Dajudaju awọn onipaṣipaarọ owó n ṣẹ́ owó oniruuru ilu ti awọn Ju ti wá si Ajọ, si aabọ̀ owó ṣekeli ti a n lò ni Tẹmpili.  (Wo Ẹksodu 30:13, 14;  2 Kronika 24:6, 9).  Iwọra fun ère ti bọ́ sinu òwò naa.  Ni ọdun mẹta lẹyin naa, ti a n wẹ Tẹmpili kan naa mọ́, Jesu wi pe, "A ti kọ ọ pe, Ile adura li a ó ma pè ile mi; ṣugbọn ẹnyin sọ ọ di ihò ọlọṣà" (Matteu 21:13).

A ni lati bọwọ fun ile-isin gẹgẹ bi ile Ọlọrun.  Jesu kò jẹ ki ẹnikẹni gbé ohun elo kọja ni Tẹmpili (Marku 11:16).  Ọpọlọpọ eniyan ni o ka ile Ọlọrun si ohun yẹpẹrẹ nipa òwò ṣiṣe tabi sisọ ọrọ ti kò tọ́ ṣiwaju isin tabi laaarin isin.  Ọpọ awọn olusin ni ile-isin ti igba lodé ni o ti sọ ile Ọlọrun di ibi yẹpẹrẹ nipa tita ọja ikore, tẹ́tẹ́ títa, ṣiṣe afẹfẹyẹ̀yẹ̀, wọn si tun mú tẹ́tẹ́ tita pẹlu wá si ile-isin gẹgẹ bi ọ̀na lati fi kó owó jọ.  A kò gbọdọ jẹ ki awọn ọmọde pariwo, tabi ṣire, tabi jẹun, tabi ṣe aibọwọ fun ile Ọlọrun lọna miiran.

Awọn Ju beere fun ami kan.  Jesu dahun pe, "Ẹ wó tẹmpili yi palẹ̀, ni ọjọ mẹta Emi o si gbé e ró."  Ni igbà miiran ti wọn tún n wá ami, Jesu wi fun wọn pe, "Nitori bi Jona ti gbé ọsán mẹta ati oru mẹta ninu ẹja; bẽli Ọmọ-enia yio gbé ọsán mẹta on oru mẹta ni inu ilẹ" (Matteu 12:40).

Bi o tilẹ jẹ pe awọn Farisi ati awọn ọmọ-ẹyin dabi ẹni ti òye ọ̀rọ yii kò yé nigba ti a sọ ọ́, lẹyin ti a kàn An mọ́ agbelebu, awọn olori alufaa ati awọn Farisi tọ Pilatu wá, wi pe, "Alàgba, awa ranti pe ẹlẹtan nì wi nigbati o wà lãye pe, lẹhin ijọ mẹta, emi o jinde" (Matteu 27:63).  Dajudaju wọn n tọka si ọ̀rọ Rẹ̀ pe, "Ẹ wó tẹmpili yi palẹ̀, ni ijọ mẹta Emi o si gbé e ró."

Lakoko ti a fi I sùn niwaju olori alufaa, awọn ẹlẹri èké gbiyanju lati jẹri gbe E pe, "Awa gbọ́ o wipe, Emi ó wó tẹmpili yi ti a fi ọwọ́ ṣe, niwọn ijọ mẹta emi o si kọ́ omiran ti a kò fi ọwọ́ ṣe" (Marku 14:58).  Dajudaju, awọn ẹlẹri èké wọnyii wà ninu awọn ti o beere àmi lọwọ Rẹ̀ ninu Tẹmpili nigba ti O lé awọn wọnni ti o fẹ sọ ile Ọlọrun di ile ọjà tita jade.

O hàn gbangba pe nipa bibeere fun oluṣọ lọwọ Pilatu, awọn Ju mọ̀ pe ọ̀rọ Jesu wọnyii tọka si ara Rẹ̀, ṣugbọn ni akoko ifisun Rẹ̀, wọn ti lo ọ̀rọ wọnyii gẹgẹ bi ẹni pe Tẹmpili ti a fi ọwọ́ kọ́ ni o fẹ wó palẹ̀.  Gẹgẹ bẹẹ ni lonii awọn eniyan n ṣọ́ Onigbagbọ́ loju mejeeji lati fi ẹsùn sùn un.

Jesu mọ̀ ohun ti o wà ninu eniyan.  Jeremiah jẹri si eyi nigba ti o kọwe pé, "Ọkàn enia kún fun ẹ̀tan jù ohun gbogbo lọ, o si buru jayi! tani o le mọ̀ ọ? Emi, OLUWA, ni iwá awari ọkàn enia, emi ni ndan inu wò, ani lati fi fun olukuluku gẹgẹ bi ọ̀na rẹ̀, ati gẹgẹ bi eso iṣe rẹ̀" (Jeremiah 17:9, 10).

**AWỌN IBEERE**

1 Ọmọ ọdun meloo ni Jesu nigba ti o ṣe iṣẹ iyanu kin-in-ni?

2 Nibo ni a ti ṣe iṣẹ iyanu kin-in-ni naa?

3 Bawo ni ilu yii ti jinna si Nasarẹti to nibi ti a gbé ti tọ́ Jesu dagbà?

4 Ta ni wà nibi igbeyawo naa?

5 Bawo ni omi ti a sọ di waini ti pọ̀ tó?

6 Njẹ "nigbati awọn enia ba si mu yó tan" fi hàn pe wọn mu amupara?

7 Bawo ni Kapernaumu ti jinna si Kana tó? si Jerusalẹmu to?

8 Darukọ ọmọ-ẹyin kan ti ile rẹ wà ni Kapernaumu.

9 Sọ awọn iṣẹ iyanu ti a ṣe ni Kapernaumu.

10 Ki ni ṣe ti Jesu lé awọn agutan ati maluu jade kuro ninu Tẹmpili?

11 Nigba wo ni a kọ́ Tẹmpili yii, ta ni o si kọ́ ọ?

12 Awọn tẹmpili wo ni a ti kọ́ gbekalẹ ṣaaju lori ilẹ yii?